# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No 781. THURSDAY AUGUST 27, 1964 (2D)


## Ẹkinyẹmi Ṣọ Pe Ẹgbẹ Ọlọpẹ Ni Yio Bori Ibo Ti Nbọ

EKO .- Oloye Akinyẹmi Akinyẹde ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti yio gbe apoti ibo silẹ lasiko idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria sọ pe ohun mẹtadinlọgọrin to le doju ija kọ ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre lasiko idibo ni o ti han kedere soju fun awọn ẹgbẹ na.

Oloye Akinyẹmi Akinyẹde sọ eyi fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre tiẹka Eko nibi ẹyẹ ipade kan tiotaawọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ni ọjọAle ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi ni ile ẹkọ giga ti St.Saviour's School pe oda on loju pe ẹgbẹ Afẹnifẹre yio bori ibo si ile Igbimọ Aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria eyiti idibo rẹ yio waiye larin Ọdun yi.

Oloye Akinyẹmi tun sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pe on lọ ṣe abẹwo Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni ọgba ẹwọn ti ilu Kalaba atipe ko sin kan to le mu awọn kurorara.

Ninu awọn olori ẹgbẹ Ọlọpẹ to sọrọ nibi ipade na Ọgbẹni Shasọrẹ fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ na pe ko si nkankan to le mu wọn bẹbẹ fun idasilẹ Olori ẹgbẹ na Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ lati ọgba wọn.

## Ipinnu Lati Tu Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ka

# BALEWA LỌ RI AZIKIWE

NSUKKA:- Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ọlọla Alhaji Abubakar lọ se abẹwo Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe ni ilu rẹ nibi ti o ti nse itọju ara rẹ ni Nsukka lori aisan kan to ṣe e laipẹ yi, Ọlọla Alhaji Abubakar ṣe abẹwo na laisọ fun gbogbo enia lati le gbọ asiko ti yio lọ fun irin ajo na eyiti Ọlọla Alhaji Abubakar si fi pada si ilu Eko ni deede agogo mẹta ọsan ọjọ aiku ti ise ọjọ kẹdọgbọn osu yi.



DOKITA NNAMDI AZIKIWE
Olori Apapọ Ijọba Naijiria

Irohin na fi ye wa pe Ọlọla Abubakar lọ ṣe ibẹwo Dokita Azikiwe lati lọ ki fun aisa ti o sẹlẹ si laipe yi. Oniwe irohin wa se alaye pe lati igbati Dokita Azikiwe ti wa ninu aisan na pe ko ti lọ se abẹwo lati lọ kii lati igbati irohin na ti jade ni ojọ kẹjọ Osu yi

Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa labẹlẹ fi ye wa pe ninu awọn nkan to ṣe gbongbo ti Ọlọla Alhaji Abubakar lọ ri Dokita Azikiwe fun ni ọrọ to jemọ eto lati tu ile igbimọ asofin ti apapọ ijọba ilẹ Naijiria ka ati eto rogbodiyan to nsẹlẹ si ipinlẹ Iwọ-Orun ilẹ Naijiria lẹnulọlọyi.

Irohin fi ye wa pe asiko ti nwọn yio tu ile igbimọ na ka si jẹ ohun to wa ni aṣiri ati pe yio jẹ Dokita Azikiwe ni kan ni yio jẹ ẹniti yio mọ asiko na.

Irohin labẹlẹ na tun fi ye wa pe ninu awọn ọrọ ti awọn olori ile Naijiria na jinroro le lori si tun jemọ rogbodiyan to nṣẹlẹ ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati paapa fun awọn olori ẹgbẹ oṣelu meji kan ti ku ni ekun Ijọba laipẹ yi ati pe iru nkan bayi jẹmọ ohun to le mu aifi ọkan awọn enia ipinlẹ na balẹ

Nigbati Ọlọla Abubakar de lati ipade ti awọn ẹgbe rẹ NPC ati awọn alabaṣepọ wọn se ni Kaduna laipẹ yi, Alhaji Abubakar fi nye awọn oniwe irohin pe nipa rogbodiyan to nṣẹlẹ ni ipinlẹ Iwo Orun Naijiria laipeyi

Wo Oju Ewe Kẹfa



ALHAJI ABUBAKAR BALEWA
Alakoso Ijọba Apapọ Ilẹ Naijiria

## Okpara Wọ Ilu Eko Gẹgẹbi Ọba!

Eko-: Ọjọ nla ni ọjọ 'Ru ti ise ọjọ Kẹrindinlọgbọn Osu yi nigbati Alakoso Ijọba ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Alakukọ ba ọkọ ofurunfu de si Ikẹja lati Enugun lati wa ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ NCNC ṣe ipade eyiti awọn igbimọ ẹgbẹ na ṣe ni ile itura ti Empire Hotel Idi-oro ni irọlẹ ana ti iṣe ọjọ Kẹrindinlọgbọn Oṣu yi.

Ni deede agogo mẹsan owurọ ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati Ọlọpẹ ti pesẹ si ile ẹgbẹ ni Yaba eyiti ofi jẹ pe awọn enia na lọ titi de Tinubu lati fun olori ẹgbẹ na ni ẹyẹ ku abọ.

Ni deede agogo mọkanla abọ ni ọkọ ofurufu ti o gbe Dokita M. I. Okpara lati Ẹnugu gunlẹ si ebute ọkọ ofurufu na ni Ikẹja. Lẹsẹkẹsẹ na ni awọn olori ẹgbẹ na ti o wa pade Dokita Okpara ti fun ni ẹyẹ ikini ku abọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na si to lẹsẹsẹ ninu mọtọ ayọkẹlẹ lati ba olori ẹgbẹ na wa si ilu Eko.

Ninu awọn Olori ẹgbẹ to lọ pade olori ẹgbẹ na ni Oloye Ben-

Wo Oju Ewe Kẹfa



DOKITA M. I. OKPARA
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

# Ẹrukobodo Pade Olotu

Ọrọ ti Ọtẹlẹmuyẹ pẹlu "Irohin - Imọlẹ" sọ jade ninu Irohin - Imọlẹ ti ọjọ kọkanlelogun oṣu August 1964 lori ẹgbẹ Oṣewe lede Yoruba dara puọọ. Ẹrukobodo lọ ri Olotu lori nipa Ọrọ na. Ibiti nwọn pari ọrọ na si niyi:-

Ẹrukobodo:- Olotu, ẹ ku Ọzinitin yi; ṣe afẹrẹ yi ko ti de ọdọ rẹ?

Olotu:- Nko gbọdọ ri otutu; Amuku ẹmu - iṣa ti ẹ fi ranṣe simi, mo ti mu lọwurọ yi, ara mi ti le giri - giri.

Ẹrukobodo:- Ohun ti mo wa ri Ọ fun ni ọrọ ti i w ọ pẹlu Ọtẹlẹmuyẹ sọ nipa ẹgbẹ Oṣewe l'ede Yoruba, e y i ti mo rii wipe, bi a ba le ṣe e yio dara pupọ

Olotu:- Ha! Ẹ ṣeun, e m i na ti sọ wipe nko ni ṣalai wa ri y i n nipa Ọrọ na, Alọgba ! kini ẹ ti ro ọrọ na si?

Ẹrukobodo:- Ṣe i w ọ na mọ wipe;- "Gbogbo orin ni Aranmu ko le kọ, ṣugbọn bi o ba di Wọnkuwọ, kosi ẹniti yio gbe Orin n a t o Aranmu"

OLOTU:- Kabiyesi! Bẹni ti nyin ri. Emi na ti sọ wipe ao ri nyin nipa idasilẹ ẹgbẹ na, ki ale mọ bi ao ti ṣe e o rẹ si.

ẸRUKOBODO:- Ko si eto kan to nbẹ ninu rẹ to ju wipe. ki ẹ fi iwe rẹ s'ode lọ.

OLOTU:- Ki afi iwe rẹ s'ode bawo?

ẸRUKOBODO:- Ohun ti mo sọ nipe, ki ẹfi iwe pe awọn enia pataki-pataki ti ẹba mọ wipe otọ ki nwọn ṣe ninu ẹgbẹ na.

OLOTU:- Ako mọ wipe ohun ti ẹsọ niyẹn, iyẹn ko soro.

BẸRẸBẸRẸ BI IṢI BERE

ẸRUKOBODO;- Kini ti Ọgbẹni Ọtẹlẹmuyẹ ti jẹ ninu ọrọ iṣẹ iwe na?

OLOTU:- Ẹ kosi bere, Iṣẹ i..e titẹ l'ede Yoruba ni on pẹlu Ọgbẹni Shoyinka nṣe, nwọn si ni inu didun fun ajọṣe pọ iṣẹ na

ẸRUKOBODO:- Olotu. ẹ ṣeun. Ọrọ ti mba ro ki nto ro ọfọ ni o ṣẹṣẹ ran mi leti yi

OLOTU:- Iru ọrọ wo niyẹn?

ẸRUKOBODO;- Ota simi leti fiorin wipe Ọrẹrẹ Ọgbẹni Shoyinka ti bẹrẹ si gbe ọwọ abiku ẹgbẹ Olo-



Ọgbẹni Ẹrukobodo

ye Akintola kiri, Bẹni, tabi rọ ni?

OLOTU:- Emi na ngbọ bẹ, ṣugbọn, nko lero wipe, ole jẹ bẹ. nitori wahala Shoyinka ti pọ fun ẹgbẹ Afẹnifẹre

ẸRUKOBODO:- Ko gbọdọ jẹ bẹ, Bi oba jẹ bẹ Odaju wipe Ọgbẹni Shoyinka fẹ ṣi ara rẹ lọna ni, nitori, Iṣu ki ibu jina tan ko wa gọ"

OLOTU:- Ẹ gbe owe nyin de. Itumọ owe yi o?

ẸRUKOBODO:- Ohun ti mo ri ki nto sọ bẹ nii wipe, bi oba di asiko yi ti Shoyinka ba fi ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ, nibo ni yio ti jẹrẹ wahala ti oti nse fun ẹgbẹ Afẹnifẹre tabi olero wipe ẹsẹ abiku duro nilẹ daada ni, tabi ko mọ pẹ Abiku tun nbọ wa ku

OLOTU:- Ọrọ na ka, ti ye mi, ao man woo na-

ẸRUKOBODO:- Olotu ẹwo ọrọ na daada o' O digba.

# Yoruba Asiko To

**Lati Ọwọ Latifu Babalọla**

Mo de
Mo ki ara ile
Mo de mo ki ero ọna
Ẹ ma ku ati jọ
Emi Akanbi Ọgan
Ọmọ Ijẹsha lọba l'ọrọ
Ọkọ Falilatu ẹlẹyinju ẹgẹ
Abani rẹ fi afo ija silẹ
Abanija ma ni ni lara
Ẹnyin ọmọ Karọ - o jire
Ẹ sumọ tosi
Ki ẹ wa gbọ
Ẹ farabalẹ
K'ẹ gbọ ọrọ atata
Asiko to fun awa ọmọ
Yoruba lati ronu
Ẹ jẹki a parapọ
Ki a ja fun ilẹ wa
Ẹ jẹki a yọ ifẹ owo kuro l'ọkan
Ka ronu jinlẹ
Nipa awọn nkan to nṣẹlẹ
Si Yoruba l'ode Oni
Ki a ranti ẹhinọla
Ani ki a ranti awọn iran ti mbọ
Ẹ ma jẹ k'a tori owo
Ka ta iran Yoruba s'oko ẹru
Owo tobi p u pọ
Ṣugbọn ko to nkan
Ẹ jẹki a parapọ
K'a di ọkan ṣoṣo
K'a jọ ja fun iṣọkan ilẹ Yoruba
K'a f'ọwọ wewọ
Nitori ẹhin-Ọla
K'a fi imọ ṣọkan
Nitori irẹpọ
Ani ki alafia ati idẹra le ma ba
gbogbo wa gbe.
K'a dibo fun ẹgbẹ Oduduwa
Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ki ijọba rere le tete pada si ipinlẹ Iwọ-Orun.
Ani K'ominira le wa fun Baba l'Ayinka
Ẹ Ṣ'anu Awolọwọ
Ẹ dibo fun Ọlọpẹ
Ẹ ranti Oore ti Baba l'Ayinka ṣe fun awa Mekunnu
O d'ọwọ gbogbo wa o
O digba, O digbo ṣe o.



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**
BABA ỌLAYINKA

# IWE SI OLOTU

## E san Owo Morgan Fun Awọn Olukọ

Olotu, Jọwọ gba mi laye diẹ ninu gbajumọ iwe rẹ ol yin mọmọ eyiti gbogbo enia Naijiria ngbadun lojojumọ lati bẹ Ijọba Apapọ ki wọn jọwọ ki nwọn san ẹgunwo owo- osu ati owo ọya osu miran ti morgan ni ki nwọn san fun awọn osisẹ.

Ọpọlọpọ awọn osisẹ orilẹ ede yi ni nwọn ti san owo morgan fun oya mi lẹnu pe nwọn ko ti san fun awọn Olukọ, bẹsi ni isẹ kan na ni awọn Olukọ nwọn si ẹtọ lati gba owo mongan gẹgẹbi Igbimọ na ti sọ ninu irohin wọn Ẹ jọwọ mo bẹ Minista Alamọjuto eto ẹkọ fun Ijọba Apapọ lati aso aye yẹ rere yi ki Ijọba si tete sna owo osu mọgan fun awa Olukọ.

Tisa Olu Mushin.

## Ẹkunwo Ọja Pọ

Ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi Ijọba Apapọ ki o ṣanu talaka ki nwọn din owo ibupe Ilu, ki nwọn si ma fikun owo ọja mọ nitori awa talaka oti di aṣa Ijọba lati ma fi kun owo awọn mẹkunu rara

Ẹlomiran owo-oṣu rẹ kere loṣu, ki oto san owo ile. owo iwọkọ ati bẹẹbẹ lọ, owo yio tan, bẹ si ni ẹlomiran ni ọmọ ni ile ẹkọ giga omiran wa ni ilu Oyinbo, eleyi nfa daduro ọpọlọpọ ọmọ ti o wa ni dalẹ



Oloye Festus Okotie—Eboh

Nigbamiran ija ama ṣelẹ ni ọja ẹlomiran yio tun pada sile nigbata owo ti omu wa si oja koba to ọja ra mọ. ẹkunwo oja ariotẹlẹ ni o nfa

Bi Ijọba ti fi owo kun owo oṣu awọn Oṣiṣẹ bẹ na ni Ijọba ba tun fi owo kun owo awọn ọja ti nwọle ati eyiti nwọn nṣe ninu ile wa

Ọpọlọpọ awọn Osiṣẹni kori owo oṣu gba ni asiko depo yio gba ẹkunwo eyiti Ọlọla Morgan ni ki awọn osiṣẹ gba

Awọn ẹlomiran ngba Pọn marun labẹ enia Dudu nigbati ẹlẹgbẹ wọn ngba ogun Pọun labẹ Ijọba tabi awọn Oyinbo Onisowo Awọn to wa labẹ Enia Dudu si pọ ju awọn to wa labe Ijọba lọ Ẹ sanu talaka ki ẹ mọ fi owo kun owo ibode mọ

Emi ni
S O Famiyẹsin
MUSHIN

## Idahun Si Ibere Ajao Amukoko.

Mba sọpe bi Olotu ba le gba mi laye diẹ ninu iwe irohin rẹ oloyinmọmọ ti o njade lojojumọ ti o kun fun ọgbọn ati oye lati dahun ibere Ọgbẹni Ajao mmukoko ti o jade ni ọjọ kerinlelogun osu yi pe tani o wule ju fun obi ninu okunrin ati obinrin

Idahun emi npe obinrin ni owulojn nitoripe, bi ọmọbinrin baji ni arọ a gba ile, a fọ awo, a gbe ọbẹ kana gbogbo isẹ ile pa tapata ọmọbinrin ni o wulọju ki ọmọkunrin to sọpe on se ọkan ninu isẹ ile ọmọbinrin ti se meji idirẹ ti mo fi sọpe ọmọbinrin ni ni owuloju fun obiju ọmọkunrin lọ ni yẹ Olotu mo dupẹ ye tiẹ gba mi o.

Ọkọ ọba ko ni sa yin lẹsẹ Amin,

Emi ni
Celinah Ronkẹ Ọrẹlaja
Ijẹbu-Imushin.

## E Tu awọn ara Eko Silẹ !

Mba sọpẹ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye ranpẹ yi ninu iwe Irohin Imọlẹ akọmọ lede lati bẹ Ijọba Apapọ paapa Minista Alamọjuto eto Alafia ilu Eko ki nwọn tu awọn ara ilu Eko sibẹ, eyi ni ki wọn ka ofin mase ipadeode gbangba ati ma wọ ode ti nwọn ti sẹ lati nkan bi ọdun meji sẹhin.

Rogbodiyan tio sẹlẹ ni. ipinlẹ Iwọ orun ni ọdun 1962 ni ofa ti Ijọba Apapọ fi sẹ ofin ko si iwọde ode gbangba igbana titi di oni

Sugbọn bi ofin na ba tun yi wa lẹko nisisiyi Bawo ni Ijọba sẹ fẹ ki awa ara Eko mura sile fun Ibo tabi Bawo ni a o tisẹ ma ri aye polow ibọ ti ao di ni ipari ọdun yi?

Nirorira mo bẹ ọgbẹni Musayau Adura Minista Alamojuto Alafia ilu Eko ati Kase ofin ma se ipade ode gbangba ti o ti mbe l'eko lati ọdun meji gehin ki a le ri aiya mura silẹ fun ibo Atundi to mbọ yi

Emi ni
AJẸGBRO DAGBA
EKO

# Akiyesi

Si Gbogbo Ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ ni Abẹokuta ati agbegbe rẹ Ti o ba fẹ ra Irohin Imọlẹ ti o njade ni Ojojumọ lọ ra lọwọ Aṣoju wa Omidan Owokọya.

Owo Bookshop
Shapon Agọ - Oko Road
ABẸOKUTA

Ti Enikẹni ni Irohin Imọlẹ, kọbọ meji pere.

# Ikede Pataki

Eyi ilati kede pe, itan igbo Ọrọ Abidodo Meje yio wa a bẹresi jade lati ọwọ Ọgbẹ i J. O. Shayinka ninu ọsẹ ti mbọ. Ki awọn onkawe wa ma a mura de itan Aladun na.

## Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe il na Ifa Iyanrin titẹ. Etutu şiṣe Iwosan ati egbogi ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku koni yọọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ọ ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja şi rere, awọn baba awon ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mọ Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko şe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ şaşa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaiya pe arun tabi Amodi kan le pa ọ Iye owo 25/-

Turari Ẹyọ u Ajẹ ti o ba nfin turari yi ba a ti şe şore rẹ Ajẹ ati abatenijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwọ ni mọ alta ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo si wa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan ati agbara Psalm ẹgun l o r i awọn Ajẹ pẹlu Ara | 3/6 30/- |
| Tailos Measurement works | 2/- 6d |
| Iwe lori iyege Ikọṣẹ (Certificate of Apprenticeship) eyọ kan | 5/- 12/- 6d mẹta |
| Iwe Adehun larin Onile ati mehaya Tenants (Agrement Form) | 10/- 6d meji |
| Iwe Aṣofofo Alejo (Visitors not Book) | 2/-6d |
| Iwe Alagbafọ (Laundry Book) | 5/-6d |
| Kadi ifisọrọ sinu redio lọfẹ | 2d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan fun itaja ati Işegun Ajẹ | 16/- |

## APEJUWE ILE IṢE WA

Wọ Bọsi ti o nlọ si Lwawanson ni Yaba 3d pere bbi ti o ba sọkalẹ ni Laianson. bere Ilu Itirẹ. Ti o tia, de Ilu Itire bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ri ile itawe wa wa. Ti o ba fẹ fi owo ranşẹ fun ọja ara adirẹsi mi niyi:—

**J. O. Shoyinka**
5, Alaba Street
Oduabọrẹ
Mushin.

# Egbẹ A. G. Unit 6 Bariga Yan Oloye Titun

BARIGA :- Irohin ko to afojuba ni ọjọ Abamẹta ti ;se ọjọ kejidelogun oşu yi nitibati awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti unit 6 Bariga ti Ward 28 Ikẹja South Constituency fe eto yiyan awọn Oloye titun fun ọdun 1964 si 1965, wọn enia to wa sibi eyẹ ipade lati yan awọn oloye titun wọn to ẹgbẹwa enia (2,000)

Ki eto lati ma yan awọn oloye na to bẹrẹ ni ọgbẹni M A Odugbẹsan ti o je akọwe agba fun Ward 28 Ikẹja South Constituency Shomolu ati ọgbẹni A Pedro ọkan ninu awọn olori ẹgbẹ Afẹnifẹre se alaye lori eto yiyan awọn oloye titun na fun awọn ọmọ ẹgbẹ na ki ọwọn to ma bẹ eto yiyan awọn oloye na lọ.

Eyi ni oruko awọn oloye na ati ipo wọn ninu ẹgbẹ na Ọgbẹni A. Ọla Akinsanya alaga, Ọgbẹni Ibiyẹmi igbakeji alaga, Ọgbẹni Faluyi akọwe, Ọgbẹni A. B. James igbakeji akọwe, Ọgbẹni Saliu akọwe Alakoso G, Ayọ Ẹfunuga akọwe eto owo, Ọgbẹni B. K. Adefuye Akapo, Ọgbẹni Olushile si wọle laisi alatako gẹgebi olusiro owo Ọgbẹni Bayọ Tiamiyu tun wọle lẹkeji gẹgẹbi akọwe eto irohin, Ọgbẹni Nuru Salisu ati ọgbẹni Owolabi Odufowora tun wọle laisi atako gẹgebi akọwe eto itan kale ẹgbẹ na.

Lẹhin ti nwọn şe eto yiyan awọn oloye titun na tan ni awọn Oloye titun na tun lo joko nibi ipo wọn titun Lẹhin ni alaga titun na Ọgbẹni A. Ọla Akinsanya dupẹ lọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ na fun ipo ti nwọn ya si ati pe ki awọn ọmọ ẹgbẹ na ni isowọpọ lati lerì pe ẹgbẹ Afẹnifẹre bori ibo ti nbọ ati pe gẹgẹbi gbogbo wọn ti mọ pe agbegbe na sora pupọ Ọgbẹni Akinsanya tun sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lo le mu ijade olori ẹgbẹ na si kegbe pe Awo!! Awo!! Awo!.

Lẹhinna ni akọwe titun tun ka iwe ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ward 28 Shomolu kọ si awọn ọmọ ẹgbẹ na lori eto idibo si ile gbimọ asofin ti Apapọ ile Naijiria ati si ti ipinlẹ Iwọ Orun pelu ti igbimọ Ijọba ibilẹ ti Mushin eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe ati sunmọ bayi.

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Ọkan ninu awọn nkan ti o ti nfẹ ki o ni, yio jẹ bẹ nitotọ, jẹki awọn ohun ti o ba ngba lero ki o ma jẹ şişe nijọmiran, mura lati gba alejo pataki kan.

PISCCS (Feb 21 - Mar 20) Şọra nitoripe inu rẹ yio ma bi gbogbo enia fi iwa rere rẹ han fun wọn, maşe jẹki nwọn gbọ pe işẹ rere ti o ti nşe fun wọn iwọ ko ni şe mọ, şọra fun jamba.

ARIES (Mar 21 - April 20) Maşe binu bẹni ki o maşe ja, pataki ni akoko owurọ maşe tọp npin tabi wadi ohun kan si ẹnikan.

TAURUS (April 21 - May 20) Ori rẹ yio ga ju ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ lọ, şugbọn şọra ki o maşe jẹri eke ni owurọ masi şe nawo inakuna, bẹni ki o maşe ra ọja awin.

GEMINI (May 21 - June 21) Yọ ibinu kuro li ọkan rẹ, nigbana iwọ yio ri ẹniti yio gba ọ ni imọran ti yio si fi ọkan rẹ balẹ nigbana, ohun ti ọ mbinu si yio tẹ ọ lọwọ, gbogbo enia yo yọnu si ọ.

CANCER (June 22 - July 23) Maşe fi işẹ pa ara rẹ lori ki awọn enia maşe ni ọkan ibinu si ọ, nşe ni ki o wa ọrẹ kun ọrẹ ki o ba maşe ri nkan ibinu ni owurọ.

LEO (July 24 - Aug 22) Maşe rin irin ajo ni akoko yi, ma si şe kuro nile lọ sibi kan. Şọra nitoripe ijọngbọn sunmọ tosi iwọ yio ni işẹ rere pupọ lati şe sa kọju si işẹ re.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Maşe fi wara wa a jasa, ronu wo daradara ki o tọ bẹ lu ọrọ sisọ, ki o si pa ibinu rẹ mọlẹ maşe fihan si ode, bi o ba ri pe ko şe şe

LIBRA(Sept24-Oct23)Iwọ yio gbo iroh n kan ti yio wọ o li ọkan şọra nitori jamba si ọ loni ohun isoro kan eda ọ lamu,

SCORPIO(Oct24-Nov22)Diẹ ninu awọn ohun ti o nro ni ọkan rẹ yio şẹ sugbọn ebun ti iwọ ko ni ireti ni yio wahala re.

SAGITTANRIUS(Nov23-Dec21)Iwọ yio sẹ orir nipa yiyege ni u işẹ kan. Mase nwọn lẹ ni inaku a masiṣe inure.

CAPNCORN(Dec22 Jan21)Ọjọ oni dara fun kankinkan to ba fẹ şe, şọra rẹ pupọ ki o ma şe jẹki ibinu lo ọkan rẹ


# Bọ Lọwọ Oso Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- meji £2/5
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titi ati etutu sise pẹlu Iwoşan 20/- meji £: 15/-
Iwe Egbogi Awogba Arun 22/- meji 40/
Turare isegun Ajẹ, Oso ati awọn aba tẹnijẹ Owa fun itaja pẹlu ati alakala Pangọjo 10/6- pakẹi 2/
Ki şe ti enia fifọn ti o ra ninu awọn ọja yi aaba ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹo
Fi owo ranşẹ si

J O. SHOYINKA
5 Alaba Street
Oduabọrẹ
Mushin.

# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI

Aworan ẹgbẹyi fihan gban gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ bi wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti ama bẹ şe igbọnşẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si lagbara pupọ lai şe iwosan rẹ patapata.



"CYCLOVEN

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ia a polowo awọn fun iwosan r şugbọn boya la le ri m wa ninu awọn egun ni o le şe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile iwosan lati lọ ke eyiti oba nyọ jade la omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbọnşẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ọjukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ teran Şuga oniruru ohun adidun pupọ, pupoju nigba kugba Jẹdijẹdi ti orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omuşu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani şeşẹ wa idi rẹ ko si danwo risi mẹta daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia lo de ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata nigboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICENE STORES
Tinubu Square Lago
Adedun Chemist
14, Workeman Street, Yaba
Waterloo Medicine Store;
8. Palmchurch Stree Lagos P O Box 333
Phone: 22878 Najeria (Ọja Ita Faji

# Eto Ẹkọ Ọfẹ

## Lati Ọwọ Agbọrandun

Ki nto ma ba ọrọ mi lọ mo bẹ nyin ki ẹ jẹki a du pẹ gidigidi lọdọ awọn ti o fi ori gba ori pọ lọjọ kinni ti nwọn da eto Ẹkọ Ọfẹ silẹ eyiti o jẹ anfani nlanfun ọpọlọpọ lọjọ oni, dajudaju ọpọ obi lo ti jẹ adun ẹkọ ọfẹ

**ẸKỌ ỌFẸ KO HA JẸ IDUNNU AWỌN IJỌBA ODE ONI BI?**

Tẹle-tẹlẹ ri ti asiko ẹkọ ọfẹ ba ku oṣu mẹta ni Ikede Ijọba yio ti ma jade ti nwọn yio tun pin iwe wẹwẹ kakiri fun iforukọ silẹ fun ọdun t'ombọ, ṣugbọn ẹ wa wo bi gbogbo rẹ ti ri lodi oni nwọn ko tilẹ fẹ ki enia ki o mọ igbati iforukọ silẹ yio jẹ bikoṣepe ọpẹ awọn Oniwe Iroh'n ti nwọn fi imu fılẹ kakiri. Irufẹ iwa bayi ko dara fun Ijọba wa rara, nitori anfani nlanla ni o jẹ fun awa Mekunnu ti a ko ni owo pupọ lati fi ran awọn ọmọ wa lọ si ile Ẹkọ giga tabi ẹni ti Ọlọrun fun lọmọ pu pọ ti ko ni owo tl yio ran gbogbo wọn lọ sile ẹkọ ewo ni ko ni dupẹ lọwọ awọn li o da ẹkọ Ọfẹ silẹ fun anfani oye ẹkọ Ọfẹ fun iwe mẹfa laisan Kọbọ, Ṣugbọn loju temi Agbọrọdun irufẹ ẹkọ Ọfẹ nbi awọn Ijọba wa ninu nitori nwọn fẹ ki mekunu mọ ohun ti o nlọ rara, ki afọju fọju ku ki awọn nikan sa ma lọ siwaju ati siwaju ṣa ni ti wọn.

Biko ba ṣe bẹ ẹnyin wọ nigbati ile Ẹkọ wa lọwọ awọn Igbimọ Ijọ tabi enia kọkan ti nwọn ngbowo lọwọ nwọn nsan owo oṣu dede fun awọn Olukọ ṣugbọn lati igbati oti di ile ẹkọ ọfẹ lati igba na ni owo oṣu awọn Olukọ ti nfa sẹhin igba miran ọjọ karun titi de ọjọ kẹwa ni nwọn nto gba owo onile wọn ati yọ wọn lẹnu titi ṣugbọn owo Ori oṣoṣu ni nwọn ngba lọwọ awọn Obi awọn Ọmọde nwọnyi ki nwọn to ko ṣenji wọn fun wọn.

Ojojumọ ni Ijọba apapọ nlọ ya owo nwọn ko ya owo Ẹkọ fun awọn Olukọ.

Nitori idi eyi gbogbo awa obi ni ọrọ na nbawi ti o ba rofe igba ko le yipada fun irọ fun fun ni eyi fun ọ igba ko lọ bi orere, o le jẹ olo wo lo ni iwọ ko ma mọ ilẹ ti yio mọ ba o lọla gbogbo lo wa nibi ti nwọn ti nṣe eto ẹkọ ọfẹ ṣugbọn nitoripe ko si wahala fun ọmọ teni ofin ti o le ti ko yeki a lo ni a o gbe si silẹ, iwọ ti o nṣe eyi mo fẹ ki o mọ daju tirẹ ni o nṣe eyi mo fẹ ki o mọ daju tirẹ ni o ṣe o ko si ti ọlọrun laipẹ mọ daju wiqe iwọ yio fi ipo ti o wa loni silẹ ofin na yio tun pada wa mu iwọ na lọla.



Ọgbẹni Aia Nwachukwu
Alakoso Eto Ẹkọ Ti Ijọba Apapọ

Nitori na mọ bẹ gbogbo ti ẹ wa nidi irufẹ eto nwọn yi pe ki ẹ to ṣe etoketo ẹ ma wo iwaju ati ẹhin ki ẹ si ma bẹ Ọlọrun ni Ijoko nyin fun itọ sọna fun rere.

Oluwa ko ran gbogbo wa lọwọ (Amin)

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni Ọgbọnjọ oṣu ọdun yi (30/8/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgboṣe Lagos.

A bẹ gbogbo ọmọ ẹgbọ ki wọn tete de nitori eto nipa ti Poto ti aṣọ ninu ipade ii o kọja.

A O si fi tayọ tayọ gba ọmọ ẹgbẹ titun ti o ba wu l'Ọkunrin ati l'Obinrin

Ẹ ku iṣẹ O

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

BERE EGBOGI ARỌN

# "VERMIZYN"

Ojulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn 'ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARỌN latanlatan tabi arọn kinisa tioma mu idiwọ wa fun ẹgbagbeje obinrin lati loyun tabi ti o ma nba oyun jẹ lara Obinrin.



Bẹsi ni egbogi yidara fun gbogbo ẹniti aran agbẹdu Iṣba-aya, ọna ọfun, sisọ lẹhin bi ake tabi aran oju pẹlu Meji irufẹ egbogi arọn yi kosi ni gbogbo ilẹ Naigeria jakejo iṣẹ rẹ si daju

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe oti re eekọnọ ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki oto lo egbogi arọn yi gẹgẹbi awọn Jaman iti oṣe ti juwe lilo rẹo Fun agbalagba nikan ni owa fun. Bere orisirisi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.

## Oloye Meji Nki Ara Wọn



Ẹniti anwo ni apa osi ti o jẹ enia dudu ni Ọgbẹni Milton Obote Prime Minista ilu Uganda, Oyinbo ti o ngba ọwọ lọwọ rẹ ni Sir Alec Douglas Home ẹniti o duro ni ọwọ ọtun ni Ọgbẹni Duncan Sandys.

